# ODO OMI IYE ATI IGI IYE

## Ifihan 22:1-21

## ẸKỌ 467 --- FUN AGBA

**AKỌSORI: "Ibukún ni fun awọn ti nfọ̀ aṣọ wọn, ki nwọn ki o le ni anfani lati wá si ibi igi iye na, ati ki nwọn ki o le gba awọn ẹnubode wọ inu ilu na" (Ifihan 22:14).**

**I Irisi Inu Jerusalẹmu Titun**

1. Odo Omi Iye n ṣàn lati ibi Itẹ́ naa jade wá, Ifihan 22:1;Gẹnẹsisi 2:10; Orin Dafidi 46:4; Esekiẹli 47:1
2. Igi Iye wà niha ikinni-keji odo naa, Ifihan 22:2; Gẹnẹsisi 2:9; Esekiẹli 47:12; Ifihan 2:7
3. Kò si ègún ẹ̀ṣẹ, kò si si oru ni ilu naa, Ifihan 22:3-5; 1 Kọrinti 15:26; Ifihan 21:25

**II Ọrọ Ọlọrun jẹ́ Otitọ Titi Lae**

1. Awọn ohun ti a fi hàn ni lati ṣẹ kánkán, Ifihan 22:6, 7;3:11; Matteu 24:27, 44
2. Johannu ṣeeṣi foribalẹ fun angẹli naa ẹni ti i ṣe ọ̀kan ninu awọn wolii, a si sọ fun un pe ki o foribalẹ fun Ọlọrun, Ifihan 22:8, 9; 19:10
3. A kò gbọdọ fi edidi di Iwe yii, nitori igba kù si dẹ̀dẹ̀, Ifihan 22:10, 11;Oniwasu 11:3; Daniẹli 12:4
4. Jesu tun sọ bi ipadabọ Rẹ̀ ti sun mọ tosi to, O si ṣe ileri ère fun awọn olugbọran, Ifihan 22:12-16; Matteu 16:27; Luku 12:37; Johannu 14:2, 3; 2 Timoteu 2:12; 1 Peteru 5:4; Ifihan 1:6; 21:4

**III Ipe Ikẹyin**

1. Ẹmi ati Iyawo paapaa jọ fi ohùn si pípe ẹnikẹni ti o ba fẹ́, Ifihan 22:17; Luku 12:8; Johannu 4:14; Iṣe Awọn Apọsteli 10:43
2. A fun ni ni ikilọ ikẹyin nipa yiyọ kuro tabi fifikún Ọrọ naa, Ifihan 22:18, 19; Deuteronomi 4:2; 12:32; Matteu 24:35; 2 Timoteu 2:16, 17
3. Ọrọ ikẹyin ti Jesu sọ, ati idahun Apọsteli naa, Ifihan 22:20, 21; Heberu 9:28

## ALAYE

**Irisi Inu Jerusalẹmu Titun**

Ninu ẹkọ ti o wà ninu Ifihan 21, a ri apejuwe kukuru nipa ilu ologo jù lọ nì, ti a n pè ni Ilu Mimọ́, Jerusalẹmu Titun. Eyi yii ṣe apejuwe irisi ode-gbangba ilu naa, titobi rẹ̀, ati kikọ́ rẹ̀. Ninu ẹkọ wa ti oni ni a ri firi awọn ohun ti o wà ninu ilu Ọrun yii.

Ni tootọ o ṣoro fun wa lati moye awọn ohun wọnni ti o ga pupọ rekọja gbogbo iriri wa ni ayé yii. Nigba ti Paulu sọji lati inu awọn iṣipaya ti o ri nipa Paradise ati Ọrun Kẹta, o ni a kò gba oun laye lati sọ awọn ohun titayọ rekọja wọnni ti oun ri ti oun si gbà. Nitori naa nigba ti a mu ki Johannu ri iru iran agbala ogo ti awọn eniyan mimọ́, oun kò sọ ohun gbogbo fun wa tán patapata nipa eto ayeraye ti o wà nibẹ. Ṣugbọn iwọ saa gbiyanju lati fi oju inu woye iru ilu ọla nla ati ologo yii gẹgẹ bi o ti ṣe apejuwe rẹ̀. Gbiyanju lati gbé aworan ibi ti o ṣe pataki ju lọ tabi ibi ti o ga ju lọ ni ọla laaarin olu-ilu yii kalẹ. Laaarin ibi ti o lọla ju lọ nì ni Itẹ́ kan wà nibi ti Ọlọrun ati Ọdọ-Agutan naa gunwa si. A ko ṣe apejuwe finnifinni nipa Itẹ́ yii, ṣugbọn bi a ti mọ̀ pe eyi ni Itẹ́ ayeraye lati ibi ti Ọlọrun Baba ati Ọlọrun Ọmọ ti n ṣe akoso ti wọn si n jọba titi lae laaarin awọn ayanfẹ mimọ́, a ni lati gbà pé ẹwa Itẹ́ yii ga rekọja eyi ti a le ṣe akawe rẹ̀.

**Odo Omi Iye**

Lati ibi Itẹ́ yii ni awọn ibukun ti n ṣàn jade, nitori idi eyi ni Johannu ṣe ri Odo Omi Iye ti n ṣàn jade, lati ibẹ wá. O ni lati jẹ pe ọkàn Onipsalmu ri imọlẹ firi nipa akoko ibukun yii nigba ti o kọ akọsilẹ yii:

> **"Ororo ile rẹ yio tẹ wọn lọrùn gidigidi; iwọ o si mu wọn mumi ninu odò ifẹ rẹ" (Orin Dafidi 36:8).**
>
> **"Odò nla kan wà, ṣiṣan eyiti yio mu inu ilu Ọlọrun dùn, ibi mimọ́ agọ wọnni ti Ọga-ogo.**
>
> **"Ọlọrun mbẹ li arin rẹ̀; a kì yio ṣi i ni idi: Ọlọrun yio ràn a lọwọ ni kutukutu owurọ" (Orin Dafidi 46:4, 5).**

A sọ gbangba ninu ọrọ ori iwe ti a kà pe ninu Jerusalẹmu titun ti a o dá, ki yoo si òkun nibẹ mọ́. Awọn odo ṣiṣàn ayé a maa ṣàn sinu òkun tabi awọn òkun nla, ṣugbọn nihin ni a tun ri ọ̀kan ninu awọn ohun ijinlẹ ti o wà ninu ilu ọrun yii: a kò sọ ibi ti odo naa n ṣàn lọ fun wa -- ṣugbọn o n ṣàn lọ titi lae ni mimọ́ pẹlu agbara rẹ̀ ti n fun ni ni iye.

**Igi Iye**

O dabi ẹni pe odo mimọ́ ti o n dán bi kristali yii pin ọna igboro nla kan ti a kò sọ gigun tabi fífẹ̀ rẹ̀ fun ni, si ọna meji. Ni eti bebe odo yii ni apa kin-in-ni ati ekeji ni igi iyanu nì wà ti n so oriṣi eso mejila ti o si n mu eso yii jade loṣooṣu, ewé rẹ̀ si wà fun imularada awọn orilẹ-ède.

Boya o le jẹ ohun iyanu ki a si maa wadii bi awọn eniyan mimọ́ ti a ti ṣe logo wọnyii yoo maa jẹun ni Ilu Mimọ yii; ati idi rẹ̀ ti o fi ṣe ohun danindanin lati tun ṣe iwosan fun awọn orilẹ-ède. Ni akọkọ, ni ọpọlọpọ igba ni Oluwa wa Jesu tikara Rẹ̀ sọrọ nipa jijẹ ati mimu ninu Ijọba Ologo naa. Olugbala paapaa, lẹyin ajinde Rẹ̀ ologo, O jẹun. Ọ̀kan ninu awọn iṣẹlẹ ti o tobi jù lọ ti a sọ nipa rẹ̀ pe yoo ṣẹlẹ ni ọjọ ti n bọ̀ ni Ase-Alẹ Igbeyawo Ọdọ-Agutan. Ohun ti o daju ni pe jijẹun yoo wà ni ilu ayeraye yii. Eso nì ti o n jade ni oṣooṣu lori Igi Iye nì jẹ́ eyi ti a le pe ni eso “iye”, eyi ti o si dara lọpọlọpọ ju ounjẹ angẹli paapaa ti awọn Ọmọ Israẹli jẹ ninu rẹ̀ lọ.

Nipa ti anfaani iwosàn ti o wà ninu ewé igi yii, ki i ṣe pe awọn orilẹ-ède kún fun aisàn ati ailera, nitori gbogbo iyoku ègun ti o fa aisàn wá sinu ayé ni a ti mú kuro. Itumọ rẹ̀ gan an ni pe o wà fun mimu ilera wá si pipé ati fun itura, ki i tun ṣe pe awọn aisàn wà ti yoo tun maa mú kuro ni igba naa.

**Awọn Ọrọ Ikẹyin**

Ni igba kẹta ninu Iwe Ifihan, a tun sọ ọ pe ọrọ wọnyii jẹ́ “Ododo ati otitọ” (Ifihan 19:9; 21:5; 22:6). Ni ibẹrẹ Iwe yii, a sọ idi rẹ̀ ti a fi kọ akọsilẹ yii: “Lati fihàn fun awọn iranṣẹ rẹ̀ ohun ti kò le ṣàiṣẹ ni lọ̃lọ̃, o si ranṣẹ, o si fi i hàn lati ọwọ́ angẹli rẹ̀ wá fun Johannu, iranṣẹ rẹ̀” (Ifihan 1:1). Nihin yii ni opin ọrọ naa a tun sọ ọ́ pe “Oluwa Ọlọrun ẹmi awọn woli li o si rán angẹli rẹ̀ lati fi ohun ti kò le ṣaiṣẹ kánkán hàn awọn iranṣẹ rẹ̀” (Ifihan 22:6). Jesu tikara Rẹ̀ fi idi eyi mulẹ ni ẹsẹ ikẹrindinlogun nigba ti o wi pe: “Emi Jesu li o rán angẹli mi lati jẹri nkan wọnyi fun nyin niti awọn ijọ.” Lọna bayii, Alaṣẹ ti o ga ju lọ fi idi ọrọ yii ti a fifun Johannu Apọsteli mulẹ. Bakan naa ni ibẹrẹ Iwe Ifihan yii ileri ibukun wà fun ẹni ti “nkà, ati awọn ti ngbọ́ ọ̀rọ isọtẹlẹ yi, ti o si npa nkan wọnni ti a kọ sinu rẹ̀ mọ́” (Ifihan 1:3). Ni opin ohun gbogbo a gbọ́ ohùn Oluwa tikara Rẹ̀ lati ori Itẹ ni Ọrun ti O n wi pe: “Ibukún ni fun ẹniti npa ọ̀rọ isọtẹlẹ inu iwe yi mọ́” (Ifihan 22:7). Gbogbo wọnyii jẹ́ àfikún si ọ̀rọ iyanju ti a sọ nigba meje bayii, “Ẹniti o ba li etí, ki o gbọ́ ohun ti Ẹmí nsọ fun awọn ijọ.”

Ni opin Iwe yii, ni ipari Ọrọ Mimọ́ Ọlọrun, ni a tun ri ọrọ ikilọ ti a ti sọ ni asọ-tun-sọ tẹlẹ: “Kiyesi i, emi mbọ̀ kánkán”, “Ìgba kù si dẹ̀dẹ̀”, “Ẹniti o jẹri nkan wọnyi wipe, Nitõtọ emi mbọ̀ kánkán.” Aa, ifẹ ailopin, aanu ati oore Olugbala wa ni pipese igbala silẹ lọna ti a kò le diyele, ni mimu wa ri firi ogo ti n duro dè wá, ati ni kikilọ ati gbigba gbogbo ayé niyanju lati mura silẹ nitori ìgba kù si dẹ̀dẹ̀!

Awọn ifihan wọnyii jẹ́ ijinlẹ pupọ, oye ati imọ angẹli ti o sọ nnkan wọnyii si jẹ́ iyanu to bẹẹ ti Johannu fi kún fun iyin to bẹẹ ti o fi wolẹ nigba meji lẹsẹ angẹli naa lati sin in. Lẹsẹkẹsẹ ni angẹli naa da a lẹkun ti o si wi pe: “Iranṣẹ ẹlẹgbẹ rẹ li emi, ati ti awọn arakunrin rẹ woli, … foribalẹ fun Ọlọrun” (Ifihan 19:10; 22:9). Bayii ni a ri i pe ohun ti o lodi patapata ni lati foribalẹ fun eniyan mimọ́ kan tabi angẹli, nitori Ọlọrun nikan ṣoṣo ni ọla yii tọ́ si.

A kò gbọdọ fi edidi di ọrọ inu Iwe yii tabi ki a fi i pamọ, nitori “Igba kù si dẹ̀dẹ̀.” Itumọ eyi ni pe, gbogbo ohun ti o ba maa gbà ni a ni lati lò lati kede Ihinrere, otitọ, ati awọn idajọ Ọlọrun ti n bọ̀. Dajudaju akoko n bọ̀ ti a o fi edidi ti yoo wà titi lae di ipo ti olukuluku wa nipa ti ẹmi: ẹni ti n ṣe aiṣootọ yoo jẹ́ alaiṣootọ titi lae ati ẹni ti n ṣe ododo yoo jẹ́ olododo titi lae. Abayọrisi meji ni iwaasu Ọrọ mimọ́ Ọlọrun maa n ni nigba gbogbo. Ó yè, o si ni agbara, ki i si fi eniyan silẹ nibi ti o gbé ba wọn. Yala ki o mu ipo wọn dara ju bi wọn ti wà ri lọ tabi ki o mu ipo wọn buru ju bi wọn ti wà ri lọ. Bi kò ba dariji ni, yoo dá ni lẹbi si i. Bi ko ba rọ ọkàn ki o si mu un ronupiwada, yoo sé aya le sinu aiṣedeedee. Bi ko ba jẹ́ itọwo iyè sinu iyè, yoo jẹ́ itọwo ikú sinu ikú.

**Ipè Ikẹyin**

Bi a ti mọ̀ pe akoko ikẹyin sun mọ etile ati gẹgẹ bi awọn iṣẹlẹ ologo bẹẹ ti n duro de awọn ti o ba mura silẹ, Iyawo Kristi dapọ mọ́ Ẹmi Ọlọrun ni nina ọwọ́ ipè alarinrin naa jade. O ti jẹ́ iṣẹ Ẹmi Mimọ́ lati maa wá Iyawo fun Ọdọ-Agutan Ọlọrun, gẹgẹ bi o ti jẹ iṣẹ iranṣẹ Abrahamu lati wá iyawo fun ọmọ Abrahamu, ti a n pe ni Isaaki. Ni ọjọ oni, Iyawo Kristi wà ninu imurasilẹ. Akoko kan n bọ̀ ti a o wi pe “aya rẹ̀ si ti mura tan.”

Ṣugbọn lonii ifẹ ọkàn iyawo Kristi ki i ṣe pe ki oun tikara rẹ̀ wà ni imurasilẹ nikan, ṣugbọn o n fẹ ri i pe a ka awọn ẹlomiran kun wọn pẹlu ki Iyawo Kristi le pésẹ̀ ki akoko naa ba le yara dé. Ẹmi ati Iyawo ko fi oju sọna fun imuṣẹ akoko yii nikan ṣugbọn wọn n fi ọwọ-so-ọwọ-pọ ṣiṣẹ ni nina ọwọ ipe si "ẹnikẹni ti o ba fẹ." Fun ẹnikẹni ti oungbẹ ba n gbẹ ni a nawọ ipe yii si, "Wá … ki o gbà omi iye na lọfẹ." Ipese naa wà fun olukuluku ọkàn ọmọ-eniyan nipasẹ eyi ti o le ri igbala; ṣugbọn eniyan le yàn funra rẹ̀, o si ni lati lo agbara naa ti a fun un lati dá yàn ati ifẹ lati wá. Dajudaju Ọlọrun ti ṣe ipa ti Rẹ̀. A ti ṣe ipese silẹ. A ti nawọ ipe naa jade. Ẹnikẹni ti o ba si fẹ le wá mu Omi Iye naa lọfẹẹ.

**Ikilọ Ikẹyin**

Lati inu ipese yii ni a fiyesi awọn Ọrọ ti Oluwa ati Olugbala wa sọ kẹyin ninu Iwe Mimọ́ Rẹ̀. Awọn ọrọ ikilọ ikẹyin ni a fun wa nipa yiyi Ọrọ ati iṣẹ naa ti O ti rán si eniyan pada. Lati gé apa kan Ọrọ Mimọ́ Ọlọrun yii sọnu, eyi ti o n tọka wa si iye ainipẹkun, ni lati ba anfaani igbala jẹ ati gbogbo awọn anfaani ayeraye ti o n pẹlu rẹ̀.

Lẹẹkan si i, ati fun igba ikẹyin, ni a tun gbọ́ ọrọ naa pe, "Nitõtọ emi mbọ̀ kánkán; Amin." Ni idahun lati inu wá si ọrọ yii, Johannu Apọsteli dahun bi ẹni pe lati inu ọkàn Iyawo naa pe, "Mã bọ̀, Jesu Oluwa." Gbogbo Onigbagbọ́ ni gbogbo agbaye ni wọn n duro ti wọn si n fi oju sọna fun ipadabọ ologo ti Oluwa wa Jesu Kristi, ko si si ileri ti o tobi ju eyi lọ jadejado Ọrọ Ọlọrun gẹgẹ bi awọn ọrọ ikẹyin Jesu wọnyii fun awọn eniyan Rẹ̀. Bi gbogbo ẹda ba n gbin ti wọn si n kerora ninu inira fun ifarahan awọn ọmọ Ọlọrun, meloomeloo ni awọn ọmọ Ọlọrun wọnyii tikara wọn yoo maa fi oju sọna fun ọjọ naa nigba ti wọn yoo bọ́ sinu ogún wọn ti wọn yoo si ri Olugbala wọn Olubukun ni ojukoju.

Iwọ ha le sọ lotitọ pe iwọ n fi oju sọna ati pe iwọ n ṣafẹri ipadabọ ologo ti Jesu Kristi? Njẹ idahun jade lati inu odo ọkàn rẹ pe, "Mã bọ̀, Jesu Oluwa"? Ifẹ gbigbona pẹlu adura igba gbogbo ti o wà ninu ọkàn awa ti o n ṣe iṣẹ Ile-Ẹkọ Ọjọ Isinmi, ati gbogbo Ijọ Apọstolic Faith ni apapọ gẹgẹ bi Onigbagbọ́ ni pe ki o le pẹlu Iyawo Kristi ti yoo maa gbadun awọn ibukún ayeraye ti a ti n kọ́ ẹkọ nipa wọn yii titi ayé ainipẹkun.

## AWỌN IBEERE

1 Ṣe apejuwe bi inu ilu Jerusalẹmu Titun ti ri gẹgẹ bi Johannu ti ri i.
2 Ọna wo ni Odo Omi Iye fi yatọ si awọn odo ti ó wà láyé?
3 Ki ni fi iyatọ saarin Igi Iye ati igi ti ó wà láyé?
4 Awọn ọrọ ikilọ wo ni a tẹnu mọ leralera ninu ori iwe yii?
5 Ta ni a nawọ ipè ikẹyin si? Ta ni na ọwọ ipe naa?
6 Ikilọ wo ni a ṣe nipa yiyi Ọrọ Ọlọrun pada?
7 Ki ni idahun Apọsteli naa si awọn ọrọ ikẹyin Jesu?